# Pọ́n-na: Àtiwáyé Àti Ìṣẹ̀dá Rẹ̀ Nínú Ewì Yorùbá

**Monísọ́lá Rónkẹ́ FÁLADÉ**
National Open University of Nigeria
Federal Capital Territory, Abuja, Nigeria
+234 8034429662 / falademonisola@yahoo.com

**DOI : https://doi.org/10.5281/zenodo.20757721**

**Àṣamọ̀**
Ọ̀rọ̀, tàbí gbólóhùn tí ó bá ti ní ju ìtúmọ̀ kan lọ ni a ń pè ni pọ́n-na. Kò sí èdè ti pọ́n-na yọ sílẹ̀. O jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá gbogbo èdè lágbàyéé. Gẹ́gẹ́ bí àbùdá iṣẹ́-ọnà, a máa ń rí pọ́n-na nínú ewì ju àwọn iṣẹ́-ọnà yóòkù lọ. Fún ìdí èyí, pépà yìí ṣe ìwádìí àtiwáyé pọ́n-na nínú ewì Yorùbá àti ìṣẹ̀dá rẹ̀ bí àwọn akéwì ṣe ń ṣàmúlò rẹ̀ nínú ewì wọn. Kí ìwádìí wa lè múná dóko, a ó lo ìwé ewì mẹ́rìnlá ti àwọn akéwì mẹ́sàn-án kọ fún pépa yìí. Tíọ́rì pọ́n-na tí william Empson ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀ tí a ṣe àfàyọ láti inú Tíọ́rì Ìfojú-Àátò-Wo-Iṣẹ́-Lítíréṣọ̀ tí àwọn onísẹ́ ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ pè ní ìlànà titun (New Criticism) ni a ó lò fún ìtúpalẹ̀ àti àlàyé àwọn ewì yìí. Pépà yi ṣe àkíyèsí pe pọ́n-na lè jẹ jáde láti ara àkànlò èdè, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, fẹ̀dádọ́gba, polisẹ̀míkì, àwọn ọ̀rọ̀ to kọ́wọ̀ọ̀ rìn papọ̀, àmì àti ẹ̀dà-ọ̀rọ̀. Àkíyési fihàn pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà ninú àkànlò èdè, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ àti ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ ni pọ́n-na ti ń jẹ jáde jù nínú ewi Yorùbá.  Ní ìkádìí, a ṣe àkíyèsí pé pọ́n-na bù ẹwà kún ewì, o sì dàbí bí ẹ̀jẹ̀ àti ẹran jọ̀bọ̀jọ̀bọ̀ tó mú kí ewì dùn.

**Kókó-ọ̀rọ̀**: Pọ́n-na, Ewì Yorùbá, Àtiwáyé, Ìṣẹ̀dá, Tíọ́rì Ìfojú-Àátò-Wo-Iṣẹ́-Lítíréṣọ̀.

## 1. Ìfáàrà

Ọ̀rọ̀, àpólà gbólóhùn tàbí gbólóhùn ti ó bá ni ju ìtúmọ̀ kan lọ ni pọ́n-na. Ọ̀rọ̀-ìperí yìí ni a ń lò fún oríṣìí ọ̀rọ̀ kan náà tí ó ní ju ìtúmọ̀ kan lọ. Ewì jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀yà lítíréṣọ̀ mẹ́ta tó wà, iyẹn, ọ̀rọ̀ geere, ewì àti eré-oníṣe. Nípa lílo ojú-inú, àwọn akéwì Yorùbá ń ṣàmúlò èròjà inú èdè, ọ̀rọ̀, àpólà gbólóhùn àti odidi gbólóhùn onípọ́n-na látàrí àti dáṣọ ẹwà ró ìpèdè wọn létí àwọn olùgbọ̀ tàbí ònkàwé wọn. A ṣe àkíyèsí pé pọ́n-na gẹ́gẹ́ bí àbùdá iṣẹ́-ọnà, máa ń farahàn nínú ewì ju àwọn iṣẹ́-ọnà yókú lọ. Látàrí èyí, a o ṣe ọ̀rínkiniwín àlàyé lóri àtiwáyé àti ìṣẹ̀dá pọ́n-na bí àwọn akéwì ṣe ń ṣàmúlò rẹ̀ nínú àwọn ewì wọ̀nyí: *Ewì* Adébáyọ̀ Fálétí *apá kíní* atì *kejì*;  *Àádọ́ta Àròfọ̀ àti Ewì Oríṣiríṣi* ti Afọlábí Ọlábímtán; *Orin Ewúro* tí  Àtàrí Àjànàkú kọ; *Àfàìmọ̀ àti àwọn àròfọ̀ míràn* ti Akínwùmí Ìṣọ̀lá; *Ẹkún Elédùmarè* Débọ̀ Awẹ́;  *Àròyé Akéwì Apá kíní* àti *kejì, Ẹ̀mí Ìn Mi Ẹ̀mí Rẹ* tí Ọlátúbọ̀sún Ọládàpọ̀ kọ; *Ìjì Ayé* Olúránkinṣẹ́ Ọlánipẹ̀kun; *Ìjálá Ògúndáre Fọ́yánmu tí* Ṣayọ̀ Àlàgbé kọ, àti *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá Apá kíní* àti *kejì ti* Wándé Abímbọ́lá. Tíọ́rì pọ́n-na tí william Empson ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀ tí a ṣe àfàyọ láti inú Tíọ́rì Ìfojú-Àátò-Wo-Iṣẹ́-Lítíréṣọ̀ tí àwọn onísẹ́ ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ pè ní ìlànà titun (New Criticism) ni a ó lò fún ìtúpalẹ̀ àti àlàyé àwọn ewì wọ̀nyí.

## 2. Tíọ́rì Tí A Lò

Tíọ́rì pọ́n-na tí william Empson ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀ tí a ṣe àfàyọ láti inú Tíọ́rì Ìfojú-Àátò-Wo-Iṣẹ́-Lítíréṣọ̀ tí àwọn onísẹ́ ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ pè ní ìlànà titun (New Criticism) ni a yàn láti ṣe àlàyé àtiwáyé àti ìṣẹ̀dá pọn-na nínú pépà yìí. Ohun tí ó jẹ tíọ́rì yìí lógún jù ni iṣẹ́ ọnà inú ìwé. Àwọn tó jẹ́ agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí rí iṣẹ́ lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọnà tó dá dúró láyè ọ̀tọ̀, tí kò ní àjọṣe kan gbòógì pẹ̀lú àwùjọ. Tíọ́rì yìí gbàgbọ́ pé ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú iṣẹ́ lámèyítọ́ ni kí wọ́n wo bí òǹkọ̀wé ṣe mọ̀ ọ́n ṣe tó, bí èdè rẹ̀ ṣe dùn tó, irú ọgbọ́n ìsọ̀tàn tó lò, bí ètò ọ̀rọ̀, ètò ohùn, àti àátò ìlà ṣe rí nínú ewì tàbí ìtàn àròsọ. Nínú

àwíjàre Eliot kan èyí tí Rylance (1987:8) yọ lò, ó ní láméyítọ́ tí ó bá jẹ́ òdodo iṣẹ́, tí ó ṣe pàtàkì, kò gbọ́dọ̀ sọ̀rọ̀ lórí akéwì bí kò ṣe ewì rẹ̀. Lára ohun tí tíọ́rì yìí fúnka mọ́ ni ajọró-ṣòótọ́, ẹ̀dà-ọ̀rọ̀, àkànlò-èdè àti pọ́n-na, àwọn wọ̀nyí wà lára ohun tó mú kí èdè ewì rẹwà, kí ó sì dùn.

Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ẹwà èdè tí pọ́n-na bù kún ewì, iṣẹ́ Empson (2003), tí ó ti ṣàlàyé oríṣìí ẹ̀yà pọ́n-na méje jẹ́ ọ̀kan gbòógì tí a lè tọ́ka sí. Gẹ́gẹ́ bí àfojúsùn àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì ìfojú-ààtò wo- lítíréṣọ̀, adùn èdè, adùn ìtàn, àti adùn ààtò ni olórí iṣẹ́ wọn. Empson (2003), ní pọ́n-na jẹ́ ojúlówó àbùdá èdè ewì, tí ó súyọ nínú àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ní ju ìtúmọ̀ ẹyọkan lọ. Ó tẹ̀síwájú pé, pọ́n-na kìí ṣe àìlera tàbí àbùkù bí kò ṣe kòṣeéémàní fún èdè ewì nítorí ó fi àbájáde bí àwọn ọ̀rọ̀ kan ṣe wọnú ara ní ìhun hàn. Ìlànà-iṣẹ́ yìí fún àwọn láméyítọ́ láàyè láti tọ ipasẹ̀ orísun pọ́n-na dé inú ìró, ètò àti ìtúmọ̀ tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àbùdá tó ya ewì sọ́tọ̀.

### 2.1. Oríkì Pọ́n-na

Oríṣìí àwọn onímọ̀ ló ti fún pọ́n-na ni oríkì, lára wọn ni Empson, Katz, Hartman àti Stock, Traugott àti Pratt, Peck àti Coyle, Owólabí àti Fáladé. Ní èrò Empson (2003), ó sọ pé:

> Ambiguity encompasses any verbal nuance, however slight, that allows for alternative reactions to the same piece of language. He further considers ambiguity as a literary device, and points out that different views can often be taken of what the words mean in a line of poetry.
>
> Pọ́n-na ni ọ̀rọ̀ ti a sọ jáde lẹ́nu bí ó ti wù kó kéré tó, tó fi àyè sílẹ̀ fún ìtúmọ̀ tó ju ẹyọkan lọ. Ó tẹ̀síwájú nípa wíwo pọ́n-na gẹ́gẹ́ bí ọnà-èdè, àti pé oríṣiríṣìí ọ̀nà ní a lè fi wo ìtumọ̀ tí ọ̀rọ̀ ní nínú ewì.

Èrò Owólabí (2005:105) (1) lórí pọ́n-na nìyí:'pọn-na ni kí ọ̀rọ̀, àpólà tàbí gbólóhùn kan ní ju ìtumọ̀ kan lọ' (2) pọn-na yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀, àpólà tàbí gbólóhùn tí kò ní ìtumọ̀ kan pàtó'. Falade, ( 2021), Sọ pé pọ́n-na máa ń fóju hàn nígbà tí ọ̀rọ̀, èrò tàbí ìhun kan bá ti fi àyè gbà ju ìtúmọ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Fún àpẹẹrẹ, ọ̀rọ̀ yìí **jẹ** lè mú pọ́n-na lọ́wọ́ tí a bá lò ó láìsí nínú gbólóhùn. Dìẹ̀ lára àwọn ìtúmọ̀ tí ọ̀rọ̀ ìṣe **jẹ** yìí le ní nìyí:

Jẹ - jẹ oyè, jẹ iyán, jẹ tẹ̀tẹ̀, jẹ tẹ́tẹ́.

Àwọn ìtúmọ̀ tí **jẹ** lè ni ló wà nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí;

1 a. Mo fẹran <u>jẹ</u> iyán títí mo fi yó
  b. Yésúfù ti <u>jẹ</u> ọba ìlú wọn
  d. Mo <u>jẹ</u> tẹ̀tẹ̀ pẹ̀lú àmàlà
  e. Mo <u>jẹ</u> tẹ́tẹ́ níbi ìdíje àná –

Oríṣìí ìtúmọ̀ tàbí ọ̀nà tí a lè gbà lo ọ̀rọ̀ ìṣe **jẹ** ní ó wà lókè yìí.

### 2.2. Orísun àti Ìṣẹ̀dá Pọ́n-na nínú Ewì Yorùbá

Gẹ́gẹ́ bí èrò Empson (1930), àtiwáyé pọ́n-na nínú ewì súyọ látàrí ọ̀pọ̀ ìtúmọ̀ tí ọ̀rọ̀ kan máa ń ní. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn akéwì máa mọ̀ọ́mọ̀ jẹ̀ kí ewì wọn mú pọ́n-na lọ́wọ́ láti lè mú kí ọ̀nà ìṣọwọ́kọ̀wé wọn yàtọ̀ sí ti ẹlòmíràn, pàápàá ti a bá wò bí wọ́n ti ń lo àtinúdá wọn láti ṣe àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ kan tí yóò ní ìtúmọ̀ bí i méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nígbà tí wọ́n bá ń gbé èrò wọn jáde sí olùgbọ̀ àtí bi wọ́n ṣe ń fi iṣẹ́ ọnà wọ̀nyí dáṣọ ẹ̀wà ró ìpèdè wọn. Àtiwáyé tàbí ìṣẹ̀dá pọ́n-na le jẹ̀ ìṣòro díẹ̀ pàápàá tí a bá wo bí ọnà àgbàṣafọ̀ àwọn èèyàn ti máa ń jẹ́ onípọ́n-na. Lórí orísun pọ́n-na, Can (1993) ṣàlàyé pé:

> Ambiguity can arise in a sentence for several reasons: through the ascription of multiple meanings to single words, through the assignment of different syntactic

> structures to a sentence …using certain expressions that may have other semantic scopes.
>
> Pọ́n-na lè jẹyọ nínú gbólóhùn fún àwọn ìdí kan...nípasẹ̀ fífún ọ̀rọ̀ kan ní ìtúmọ̀ tó pọ̀, nítorí àti fún ìhun gbólóhùn kan ní ìtúmọ̀ oríṣiríìṣí...nípasẹ̀ lílo ọ̀rọ̀ tó ṣeéṣe kí ó ní oríṣìríìṣí ìtumọ̀.

Lójú ìwòye Ullman (1970) lára ibi ti a tí lè ṣe àwàrí pọ́n-na ní bí èdè ṣe ń dún, ìyẹn bí ìhun gbólóhùn ṣe ń dún jáde nígbà tí a bá ń ṣafọ̀. O ṣéeṣe nígbà mìrán kí oríṣìí ọ̀rọ̀ méjì ní ìtúmọ̀ kan náà. Èyí si lè mú àríyànjiyàn lọ́wọ́. Síwájú sí i, àpólà gbólóhùn tàbí odidi gbólóhùn méjì lè dún bákan náà ṣùgbọ́n kí ìtúmọ̀ wọ́n yàtọ̀ síra. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí;

2. (i) Ẹnikẹ́ni kó máṣe **yà** wọ́n (nínú ìjàkadì
   (ii) Ẹnikẹ́ni kó máṣe **yà** wọ́n (àwòrán/fọ́tò wọn)

Nídìí èyi, pọ́n-na lè wáyé nípasẹ̀ àwọn wọ̀nyí:

(i) Àkànlò èdè
(ii) Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́
(iii) Fẹ̀dàdọ́gba
(iv) Polisẹmí
(v) Àwọn ọ̀rọ̀ to kọ́wọ̀ọ́ rìn papọ̀
(vi) Ìfàmìsí
(vii) Ẹ̀dà-ọ̀rọ̀

**3. Àkànlò Èdè**

Àkànlò èdè jẹ́ àwọn ìpèdè tí kò ṣe é túmọ̀ pẹ̀lú ojú èrèfèé nípa àwọn ọ̀rọ̀ tó wà nínú wọn. Yusuf (2002) ṣàpèjúwe àkànlò èdè gẹ́gẹ̀ bí àwọn ọ̀rọ̀ tí a ò lè lóye nípa wíwo ẹyọ ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó wà nínú wọn. Ìyẹn ní pé, àpapọ̀ ìtúmọ̀ ọ̀rọ̀ tó wà nínú àkànlò èdè díjú, wọn kì í sáába ṣe àkìdélẹ̀ èrò olùsọ, ìdí ni pé àkùdé gbólóhùn tàbí àpólà ìṣe ní wọn jẹ́. Ní ojú ìwòye Akanmu (2014) ó ní àkànlò èdè jẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ tí ìtúmọ̀ wọn farasin. Àkànlò èdè àti àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ kì í sáába já geere, bákan náà, ìtúmọ̀ wọn máa ń mú pọ́n-na lọ́wọ́. ọ̀kan lára ìṣòro tó máa ń dójúkọ àwọn akéwì nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àkójọ ewì wọn ni oríṣiríìṣí ìtúmọ̀ ti ọ̀rọ̀, àpólà àti gbólóhùn lè ní. Láti má fi ọ̀rọ̀ ṣòfò, wọ́n á yan ọ̀rọ̀ tó ṣe wẹ́kú pẹ̀lú èrò wọn ní ọ̀gangan ìbi tí wọ́n ti fẹ́ lo ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. Àpẹẹrẹ kan nìyí; **kẹ́rù sọ́kọ̀** tí ó túmọ̀ si **ikú**. Síbẹ̀, ìtúmọ̀ rẹ̀ pé oríṣiríìṣi gẹ́gẹ́ bí a ti ri nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí. Nínú èwì Ọlátúbọ̀sún tó pè ní 'Nísulọ́kà', ó sọ̀rọ̀ nípa àwọn obìnrin tí àwọn okùnrin ń padé lójú agbo pé, ní ọ̀pọ̀ ìgbà irú àwọn obìnrin bẹ́ẹ̀ kì í jẹ́ aya rere:

3 (i) Ẹni tó fẹ́ ọkọ
Ẹni tó fẹ́ aya
Láti inú abàa Fọ̀tẹ̀dó
Ọ̀tẹ̀ ni yóò fi kó déléè rẹ̀
Ọ̀tẹ̀ ni yóò fi **kẹ́rù sọ́kọ̀**
Ìyàwó táa fo ìgànná fẹ́ (Ọlátúbọ̀sún, 2002:22)

Nínú àpẹẹrẹ òkè yií **kẹ́rù sọ́kọ̀** tumọ̀ sí; jáwèé, lọ tàbí kọni sílẹ̀ (kí obìnrin kọ ọkọ tabi kúrò nílé ọkọ)

Bákan náà nínú "Nǹkan ti Sọnù" tí Olurankinṣẹ́ kọ, akéwì yìí lo ewì yí láti sọ ẹ̀dùn ọkan rẹ̀ lórí àbùkù tí ọ̀làjú kó bá àṣà àti ìṣe Yorùbá. Ó ní ìwà rere ti ń lọ sóko ìgbàgbé láàárín àwùjọ wa:

(ii) Ọ̀làjú ń wọlé dé
Ìwà rere ń **kẹ́rù sọ́kọ̀**
Fínnífínní ń kógbá sílé
Fìrìfirì ń gba òde kan (Olúránkinṣẹ́, 2004:1)

Bákan náa ni ọmọ ṣorí nínú ewì "Bí mo bá lówó" tí Débọ̀ Awẹ́ kọ tí ó wà nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

(iii) Èdùmàrè dákun gbọ̀rọ̀ mi rò
Ṣe mí lólówó kí n tó **kẹ́rù sọ́kọ̀**
Má fowó yàn mí lójú (Awẹ́, 2009:4 )

Nínú àwọn àpẹẹrẹ mẹ́tẹ̀ẹta òkè yìí, **kẹ́rù sọ́kọ̀** ní ìtúmọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ní àpẹẹrẹ (i) ó túmọ̀ sí pé obìnrin tí a fẹ́ lọ́nà àìtọ́, lé má pẹ́ nílé ọkọ tí yóò fí kẹ́rù rẹ̀ lọ (Jáwèé), nínú àpẹẹrẹ (ii), ó túmọ̀ sí pé ìwà rere ń lọ sóko ìgbàgbé láwùjọ wa, nínú àpẹẹrẹ (iii), akéwì ń rawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí Ọlọ́run kí ó ṣe òun ní olówó ki o tó kú.

Tí a bá wo àpẹẹrẹ míràn láti inú ewì "Kábíyèsí Oyekan Kejì" ti Afọlabi Ọlabimtan kọ,

4 (i) Atẹ́rígbadé, Ọba tó ju Ọba lọ
Àgbà oyè t'ó f'àgbà mẹ́rìndínlógún **dúró**
T'ó f'ọ̀rúnmìlà ṣe ìtẹ̀sẹ̀ oyè (Ọlábímtán,1969:12)

(ii) **Ojú mi là lónìí**, mo tẹ́
Nwọ̀n gbé dígí sí mi níwájú
Mo wá rí'ra mi gedegbe (Ọlábímtán, 1969:52)

Nínú àpẹẹrẹ (i) **Dúró** jẹ́ àkànlò èdè láti fí Ọba yìí hàn gẹ́gẹ́ bí Ọba tó ń fi Ọba jẹ, tí ó túmọ̀ sí pé Ọba tó fi Ọba mẹ́rìndínlógún jẹ. Ẹ̀wẹ̀, ọ̀rọ̀ ìṣe yìí; **Dúró** jẹ́ pọ́n-na ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ tó tún ní oríṣiríìṣi ìtumọ̀ ní ọ̀gangan ibi tí a bá ti lò ó. Nínú àyọlò òkè yìí ó lè túmọ̀ sí:

a. Kó wà lórí ìdúró
b. Kí wọ́n lò ó gẹ́gẹ́ bi onídúró/onígbọ̀wọ́ fún ẹnìkan.

Tí a bá wo àpẹẹrẹ (ii), **ojú mi là** jẹ́ àkànlò èdè níbí, tí ó lè túmọ̀ si

a. Kí ojú tí kò ríran tẹ́lẹ̀ là (ìtúmọ̀ èrèfèé)
b. Kí wọ́n lo ẹnìkan gẹ́gẹ́ bí onídúró/onígbọ̀wọ́ láti yá owó tàbí ohunkóhun

Tí a bá wò ó dáradára, a ó rí i pé àwọn ìtúmọ̀ méjéèjì, ìyẹn, ìtúmọ̀ èrèfèé àti ìtúmọ̀ àkànlò ló mú pọ́n-na lọ́wọ́. Tí ó túmọ̀ sí pé, wọ́n ní ìtúmọ̀ méjì. Pẹ̀lú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, a o ri pe àkànlò èdè rẹwà, bẹ́ẹ̀ ni ìtúmọ́ wọn máa ń yàtọ̀ sí ìtúmọ̀ lèrèfèé. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, a ò le ṣàdédé sọ ìtúmọ̀ wọn, nítorí wọ́n máa ń ṣe àkìdélẹ̀ èrò olùsọ/akéwì, wọ́n tún ń lò ó láti fi ṣe àgbéyọ èrò wọn kó lè rínlẹ̀ lọ́kàn olùgbọ́ tàbí òǹkàwé. Nítórí ìtúmọ̀ méjì (ìtúmọ́ èrèfèé àti ìtúmọ̀ àkànlò) tí àkànlò èdè ni, a le sọ pe àyọrísí rẹ̀ mú pọ́n-na lọ́wọ́. Gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àríwòye Raymond (1991), pe lítíréṣọ̀ kò wà fún ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́; olórí iṣẹ́ rẹ̀ ni láti fi ẹwà lítíréṣọ̀ hàn. A rí àrídájú èyí nínú àwọn ìtúmọ̀ tí àkànlò-èdè wọ̀nyí ni nínú àpẹẹrẹ àwọn ewì òkè yìí.

**3.1. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́**

Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí a lè pè ni àtiwáyé/ìṣẹ̀dá pọ́n-na. Ọlabọ́dé (1981) ṣàlàyé àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ọ̀rọ̀ ti a ti máa ń pe ohun tàbí ẹni tí a fi wé ara wọn ní ohun tàbí ẹni náà gan-an. Ní èrò Ọlatunji (2005), ó ní nínú àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ ni a ti máa ń ṣàpèjúwe nǹkan, ojúṣe tàbí ọ̀gangan ni ọ̀nà ti yóò fi jọ ohun mìíràn Èrò àti ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ ní nkàn ṣe tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìtúmọ̀ adámọ́, ìtúmọ̀ méjì ló wà, ìyẹn, ìtúmọ̀ adámọ́/ èrèfèé àti ìtúmọ̀ àkànlò, àwọn olùgbọ̀ tàbí òǹkàwé ni yóò wo ìtúmọ̀ tó bá ohun tí wọ́n ń kà mu. Ti a bá fi ojú inú wò o, gẹ́gẹ̀ bi èrò Falade (2021),  àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ dàbí ẹni pé ó ni ìbátan pẹ̀lú pọ́n-na àti àwọn ọ̀rọ̀ tí kò ní ìtúmọ̀ kan pàtó pàápàá ti a bá wo ìbáṣepọ̀ rẹ̀ pẹ̀lu pọ́n-na àti bi ò ṣe fìdí múlẹ̀ nínú litireṣọ̀.

Gẹ́gẹ́ bí i pọ́n-na, a ò lè sọ bóyá ọ̀rọ̀ kan jẹ́ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí ìtúmọ̀ adámọ́ tí irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ bá dá dúró, a nílò láti wo ọ̀gangan ipò ti a ti lò ó. Púpọ̀ ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá àti àwọn èdè míràn ló máa ń mú pọ́n-na lọ́wọ́ nítori ítúmọ̀ méjì tí wọ́n máa ń ní, ìyẹn, ìtúmọ́ èrèfèé àti ìtúmọ̀ àkànlò.  Ìtúmọ̀ adámọ́ wà lórí ìtúmọ̀ tí àwọn èlèdè fún irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀, nígbà ti ìtúmọ̀ àkànlò gbára lé ìtúmọ̀ ohun tó bá fara jọ tàbí tí ó lè bá irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ rìn papọ̀. Àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí láti inú ewì Faleti ti àkọlé rẹ̀ jẹ́ :Ikú" yóò fìdí àlàyé wa múlẹ̀.

5. Mo rántí ikú àwọn ọ̀dọ́
   Mo rántí ọjọ́ tíná ọmọ jómọ tó jábiyamọ
   Béǹìyàn ó ṣòfò ògùrọ̀
   Wọn a ní k'Ólúwa ó má jágbè ó fọ́
   À á ti ṣe tí a kìí fi ṣì sọ
   Níjọ́ tí ládugbó ẹni fọ́ tomitomi
   Ìkàyà bí ọjọ́ ikú àbíkú àgbà      (Fálétí, 1982:53)

Ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nídìí yìí, **Ládugbó ẹni fọ́ tomitomi,** lè jẹ̀ ìtúmọ́ èrèfèé àti ìtúmọ̀ àkànlò. Lèrèfèé, ó lè jẹ́ ìkòkò tí wọ́n fi ń pọn omi, tó fọ́ tòun tí omi nínú, lọ́nà kéjì ẹ̀wẹ̀, ò lè jẹ̀ àfiwe ẹlẹ́lọ̀ọ́, tí ó túmọ̀ si aboyún tí ó kú pẹ̀lú ọlẹ̀ inú rẹ̀.
Àpẹẹrẹ míràn ni a rí nínú ewì Faleti, Ìjàmbá Odò Ọbà, ti Faleti fi dárò ìjàmbá ọkọ̀ tó ṣẹlẹ̀ ní odò ọ̀bà tí o mú ẹ̀mí ọ̀pọ̀ ọ̀dọ́ lọ:

6. Níjọ́ tẹ́rù Ògún ti ń bà mí, ko ṣẹ ní
   Níjó tó **palábẹ́rẹ́**, tó **fabẹ́rẹ́** jóná
   Tó **pẹlẹ́lẹ̀**, tó **fẹ̀lẹ̀** ya gbẹrẹngẹdẹ bí aṣọ
   Tó yàkísà tó fi dí ìdí àdán      (Fálétí, 1982:1)

Nínú àyọlò òkè yìí, **alábẹ́rẹ́** dúró fún dókítà tàbí nọ́ọ̀sì, **abẹ́rẹ́** dúró fún igi abẹ́rẹ́ àti abẹ́rẹ́ tí wọ́n ń gbà fún aláìsàn. Ṣùgbọ̀n nínú àyọlò yìí, akewì fi alábẹ́rẹ́ wé ọkùnrín àti abẹ́rẹ́ wé nǹkan ọmọkùnrin; **ẹ̀lẹ̀** fún obìnrin àti ẹlẹ́lẹ̀ fún nǹkan ọmọbìnrin. Láti fún wọn ní ìtúmọ̀ ọ̀tọ̀ sí ohun tí a mọ̀ wọ́n mọ́.
Àpẹẹrẹ míràn ní a rí nínú "Òṣùwọ̀ èkè" ti Debọ̀ Awẹ́;

7. Mo fẹ́ fojú ìkà hàn
   Kẹ́ẹ le màwọn **lékèélékèé èèyàn**
   Kẹ́ le mohun wọ́n ṣe níkọ̀kọ̀      (Awẹ́, 2009:31)

Ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nínú àyọlò òkè yìí, lè túmọ̀ sí;

(i)  lékèélékèé èèyàn – òpùrọ́ tàbí èèyàn burúkú
(ii) lékèélékèé èèyàn – àfiwé fún ẹni tó ní ìwà pẹ̀lẹ́ tàbí olóòtọ́ èèyàn

A ṣẹ̀dá ìtúmọ̀ àkọ̀kọ̀ nípasẹ̀ ìlànà fonọ́lọ́jì nípa ṣíṣe àpètúnpè fún:

ní + èké + ní èké = lékèélèkèé.

Ìtúmọ̀ kéjì ṣeéṣe kí ó jẹ́ àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tí akéwì ṣe àfàyọ rẹ̀ láti ara ẹyẹ lékèélèkèé, láti fi àwọn ènìyàn tó ń sọ̀rọ̀ nípa wọn wé olóòtọ́ àti oníwà mímọ́ bí i ẹyẹ lékèélèkèé tó dúró fún mímọ́ àti àìlábàwọ́n. Ṣùgbọ́n nínú àyọlò yìí, akéwì ń tọ́ka sí àìṣòótọ́ọ́, àì-ní-ìgbọ́kànlé àti àwọn alágàbàgebè èèyàn tí wọ́n fojú fẹ́ni ṣùgbọ́n tí ọ̀rẹ́ wọn ò dénú. Láì mọ̀ọ́mọ̀, akéwì yíì fún ọ̀rọ̀ yí ní ìtúmọ̀ míràn, ìyẹn, olóòtọ́ àti oníwà mímọ èèyàn bí i ẹyẹ lékèélèkèé tó dúró fún mímọ́ àti àìlábàwọ́n. Tí a bá tún wo "Ohun ẹgbẹ́ mi ṣe ng ka ṣàìṣé" tí Ọlabímtan kọ, a rí àpẹẹrẹ yìí:

8. Arógunmátìdi, ọkọ Ìdòwú
   Adék'áyà-ó-já **<u>ọmọ awo</u>** (Ọlábímtán, 1977:61)

Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ ni ọmọ awo tí a fàlà sí nídìí, tí a lè túmọ̀ sí:

(i)Ọmọ tí awo bí
(ii) Ọmọdé tí ó jẹ́ awo
(iii)Ọmọ tí ó ń gbé lọdọ awo.

Nínú àyọlò òkè yìí, akéwì fẹ́ ṣe àfiwé ẹni tí wọ́n ń kì gẹ́gẹ́ bí awo tó gbójú gbónu nítorí àyè rẹ̀ nínú ẹgbẹ́. Tàbí ẹni ti kì í ṣe awo, ṣùgbọ́n, tó ti bá awo jẹ, bá awo mu, nípa bẹ́ẹ̀, ki ó pè é ni ọmọ awo. Àlàyé wọ̀nyí fihàn pé àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ jẹ́ ọ̀nà míràn ti pọ́n-na fi ń wáyé. Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa pọ́n-na, ohun tí a ní lọ́kàn ni àwọn ọ̀rọ̀ méjì tí wọ́n jẹ́ ẹ̀dá kan náà pẹ̀lú ìtúmọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tàbí ọ̀rọ̀ kan tí ó ní oríṣiríìṣi ìtúmọ̀ tó súnmọ́ ara pẹ́kípẹ́kí gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ẹ̀dà kẹ́ta nínú oríṣìí ẹ̀dà pọ́n-na méje ti Empson (2003) ṣàwárí.

### 3.2. Fẹ̀dàdọ́gba

Fẹ̀dàdọ́gba jẹ́ ọ̀nà míràn ti pọ́n-na gba wáyé. Fẹ̀dàdọ́gba ni ọ̀rọ̀ tí ó fi ìrísí atí dídún jọ ọ̀rọ̀ míràn tí ìtúmọ̀ rẹ̀ yàtọ̀. Púpọ̀ àwọn onímọ̀ ló rí fẹ̀dàdọ́gba àti Ọlọ́pọ̀-ìtúmọ̀ (polisẹ́mì) gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà tàbí pọ́n-na, lára wọn ni Ulman (1975), Lyons (1997), Saeed (2003), Frath (2000) àti Falade (2021). Frath (2000) ṣe ìwádìí oríṣìí pọ́n-na mẹ́ta tí ó jẹ́ ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ kan , ó pè é ní fẹ̀dàdọ́gba, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ àti àfidípò, o parí ìwádìí rẹ̀ pé; fẹ̀dàdọ́gba àti àfidípò súnmọ́ pọ́n-na ọlọ́rọ̀-kan àti wípé àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ wà láàárín. Fromkin àti Rodman (1993) rí fẹ̀dàdọ́gba gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ tó fara jọ ọ̀rọ̀ míràn nígbà tí a bá kọ ọ́ sílẹ̀ àti tí a bá pè é, ṣùgbọ́n tí orísun àti ìtúmọ̀ wọn yàtọ̀ síra. Ní èrò Crystal (1992), ó ni fẹ̀dàdọ́gba ni ọ̀rọ̀-ìperí ti a lò nìgbà ti a bá ń ṣe ọ̀rínkiniwín àlàyé fún àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tó ní ìrísí kan náà ṣùgbọ́n tí ìtúmọ̀ wọn yàtọ̀ síra wọn. Àkíyèsí wa lóri oríkì àwọn onímọ̀ méjèèjì yìí ni pé: ó kéré tán, ọ̀rọ̀ méjì tó yatọ̀ gbọ́dọ̀ wà, ṣùgbọ́n tí ìhun wọn jọra. Àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí gbọ́dọ̀ jọra ní ìpele fònẹ́tíìkì ṣùgbọ́n kí wọ́n yàtọ̀ ní ìṣẹ̀dá àti ìtúmọ̀. Tí ọ̀rọ̀ méjì bá yàtọ̀ síra wọn ní pípè ṣùgbọ́n tí wọ́n túmọ̀ sí ohun kan náà bí i **Ọ̀jọ̀gbọ́n à**ti **Ọ̀mọ̀wé**, ọ̀rọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n. Bákan náà, ọ̀rọ̀ méjì tí dídún wọn jọra ṣùgbọ́n tí wọ́n túmọ̀ sí nkàn ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, bí **Ọlọ́rọ́** (ẹní tó ni owó àti dúkìá) **Ọlọ́rọ̀** (ẹni ti a lè finú tán), a lè sọ pé ọ̀rọ̀ wọ̀nyí yàtọ̀ síra wọn. kíkọ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ lọ̀kọ̀ọ̀kan kò ṣe pàtàkì bí kò ṣe pípè wọn. Fún ìdí èyí, **pèrò** ( kíkó èèyàn jọ sójú kan) **pèrò** (ríronú lórí ohun kan) jẹ̀ ọ̀rọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

Fromkin àti Rodman (1993), Scheffler (1979) gbìyànjú lati wá ojútùú si ìdàrúdàpọ̀ tó súyọ láàárín àárọ̀ (sínónímì) àti pọ́n-na. Ìṣòro tó súyọ lórí àwọn ọ̀rọ̀ tó jọra jẹ́ àra ìṣòro tí ó dojúkọ pọ́n-na. Ní ti àárọ̀, òun ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tó ní ìtúmọ̀ kan náà, ní ti pọ́n-na; òun ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ kan tó ni

ìtúmọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Èkíní ń béèrè fún ọ̀rọ̀ méjì tó ní ìtúmọ̀ kan náà, nìgbà tí ìkéjì ń sọ̀rọ̀ nípa ọ̀rọ̀ tó yàtọ̀ ṣùgbọ́n tí ìtúmọ̀ wọn jẹ̀ ọ̀kan náà.

Lákòótán, a lè wo pọ́n-na gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ tí ìhun rẹ̀ jọra ṣùgbọ́n tí ìtúmọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ síra wọn. Nítorí náà, fẹ̀dàdọ́gba ni ọ̀rọ̀ tàbí èrò méjì to yàtọ̀ síra wọn ṣùgbọ́n tí wọ́n ń jẹ́ orúkọ kan náà. A rí àpẹẹrẹ èyí nínú ewì "Ẹ ǹlẹ́ ń bẹ̀un" tí Ọlabimtan kọ tó fi gba àwọn èèyàn níyànjú láti máṣe fi ọ̀wọ́ tó ń dùn wọ́n sínú aṣọ, kàkà bẹ́ẹ̀, kí wọ́n sọ ìṣòro wọ́n síta ki wọ́n lè rí olùrànlọ́wọ́:

9 (a) Ajífọwọ́lẹ́rán ní ẹ fi mí sí bí ẹ ti bá mi
Ó ro 'wájú ọ̀rọ̀, ó fọwọ́lẹ́rán
Ajígbó ro ẹ̀yìn ọ̀rọ̀, ó **<u>fẹ̀hìntì</u>**
Àṣá wá doríkodò, ó ń wòṣe ẹye (Ọlábímtán, 1969:53)

Fẹ̀dàdọ́gba ni a fàlà sí nídìí nínú àyọlò òkè yìí, tí ò lè túmọ̀ sí:
(i) Ó fẹ̀yìn ti nkàn nígbà tí gbogbo ohun tí ó ń rò sún un.
(ii) Ó fẹ̀yìn tì lẹ́nu iṣẹ́, nígbà tí àkókò rẹ̀ tó.

Àpẹẹrẹ míràn ní a rí nínú "Gòkè Àjàdí Nílé Mọtẹ́lẹ̀", tí Ọlatubọsun sọ̀rọ̀ nípa bí Gòkè ṣe fi ìfẹ́ hàn sí olólùfẹ́ rẹ̀ Àbẹ̀ni àti bi Àbẹ̀ní ò ṣe juwọ́ sílẹ̀ fún un:

(b) Bórí wa bá pé tán,
Ká jọ máa ránbi aṣọ gbé ya
Ìfẹ́ **dùn** pọ̀
Níbi ẹ́ni méjì bá gbé wèrè pọ̀ (Ọlátùbọ̀sún,1977:54)

Àti èyí ti a rí nínú Àtàrí Àjànàkú:

(d) Wọ́n kàwè nítòótọ́
Wọn ò kàn lákàwé ni
Rẹ́kórí tó **dùn** wọ́n
Ló jẹ́ kí wọn ó pòfo rẹ́kọ́nà (Àtàrí Àjànàkú, 1998:16)

Fẹ̀dàdọ́gba ni a kọ yàtọ̀ ní àpẹẹrẹ (b) àti (d). **Dùn** ní (b) túmọ̀ sí àìní, nígbà tí (d) túmọ̀ sí Adùn tàbí Ìgbádùn. Àyọrísí ìtúmọ̀ méjì ti fẹ̀dàdọ́gba òkè yìí ni pọ́n-na. Àpẹẹrẹ yìí wọ́pọ̀ nínú ewì.

**3.3. Polisẹ́mì (Ọ̀rọ̀-onítumọ̀-púpọ̀)**

Polisẹ́mì jẹ́ èdè-ìperí fún ọ̀rọ̀ kan tó ni ìtúmọ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, àti fún agbo ọ̀rọ̀ tàbí àpólà gbólóhùn ti ìtúmọ̀ wọn yàtọ̀ síra wọn. Ó tún jẹ́ àbùdá kan tó súyọ lara àwọn ọ̀rọ̀ kan tàbi àpólà gbólóhùn tí o ni ìtúmọ̀ tuntun. Àwọn onímọ̀ kan rí i gẹ́gẹ́ bi àtinúdá fún ṣíṣẹ̀dá pọ́n-na. Lára wọn ni Ullam (1970), Mokgokong (1975), Leacock (2000) àti Oyè (2016). Mokgokong (1975) ní polisẹ́mì jẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ kan tí ó ní ìtúmọ̀ oríṣiríìṣí. Ó ní ibikíbi tí a bá ti ń sọ̀rọ̀ polisẹ́mì, ó ṣeéṣe kí ìtúmọ̀ kan jẹ́ ìpìlẹ̀, kí ìtúmọ̀ kéji jẹ́ àyàbá. Polísẹ́mì ni a sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ ti èrò méjì bá ti súyọ lórí ọ̀rọ̀ kan, níwọ̀n ìgbà tí ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ bá ti ní jú ìtúmọ̀ kan lọ, ó jẹ́ onípọ́n-na nìyẹn. Ó ṣòro láti ya pọ́n-na ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ kan sọ́tọ̀ si polisẹ́mì nítorí ìjọra wọn, ìyẹn ni pé wọ́n ní ítúmọ̀ méjì. Nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí, ìtúmọ̀ tí **Orí** ní pọ̀.
Nínú "Ìjà Ìlara", Ọlabimtan sọrọ̀ nípa àwọn ti ó fẹ́ràn láti máa ba ẹlòmìràn jẹ́ nítorí ìfẹ̀ ànikànjẹ nípa lílo ìtàn Ìjàpá:

10. (a) Ṣé mo ti sọ fún ọ kí o kúrò l'ẹ́hìn ọká
O wá ńronú nígbà kò jẹ́ k'o j'àkùkọ
Bí ẹ bá gb'**órí** fún mi
Wéréwéré l'o ó jẹ àkùkọ
Wàràwàrà l'o jọbẹ̀ t'o dùn (Ọlábímtán 1969:32)

Bákan náà nínú Ògúndá Méjì, Abimbọla sọ̀rọ̀ nípa ìṣòro tó kojú Ọ̀rúmìlà, àti bí wọ́n ṣe ní kí ó rúbọ sí Orí rẹ̀, bí ìṣòro náà ṣe yanjú lẹ́yìn tó ru ẹbọ náà:

(b) Ọ̀rúnmìlà ní níjọ́ tí èèyàn tií kú
Ta ni wọn gé orií rẹ̀ẹ́ lẹ̀?
Ifá ní **orí** o,
**Orí** nìkan
Ló tó alaàsàn bá ròkun
Bí mo bá lówó lọ́wọ́,
**Orí** ni n ò rò fún;
**Orí** mi ìwọ ni.
Bi mo bá bímọ láyé,
Ire gbogbo tí mo bá rí láyé
**Orí** ni ń ó rò fún;
**Orî** mi ìwọ ni,
**Orí** pẹ̀lẹ́ Àtètè níran
Àtètè gbe ni kòòṣà
Kò sóòṣà tíí danigbè
Lẹ́yìn **orí** (Abímbọ̀lá, 1972:60)

Nínú Ọ̀yẹ̀kú Méjì, Abimbọla sọ̀rọ̀ nípa àwọn Òrìṣà méjì tí wọ́n lọ dífá kí wọ́n má bà á kú ikú òjijì, Àgbà-yẹ̀kú-yẹ̀kú-orí-ìgbá àti ìgbá-ò-wó-àgbà-yẹ̀kẹ̀tẹ̀-ò-sọ̀kalẹ̀, nígbà tí wọ́n rúbọ tán, ẹbọ wọ́n gbà, wọ́n ń kọrin yin Ifá báyìí pé:

(d) Ikú té **orí** ìgbá
Ìgbá gbìràmù ńlẹ̀
Ikú té **orí** apá
Apá gbìràmù ńlẹ̀
Ikú té **orí** ooro
Ooro gbìràmù ńlẹ̀ (Abímbọ̀lá, 1968:32)

Nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, **Orí** túmọ̀ sí **Olórí** nínú àpẹẹrẹ (a), ní (b) ó túmọ̀ sí **Orí**, ìyẹn ẹ̀yà ara, nígbà ti (d) túmọ̀ sí **Ṣónṣó orí nkàn**. Gẹ́gẹ́ bí a ti ri nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, tí ọ̀rọ̀ kan bá ṣe àfihàn ìtúmọ̀ tó jọra ni ọ̀pọ̀ ìgbà, polisẹ́mì (Ọ̀rọ̀-onítumọ̀-púpọ̀) ni ayọrísí rẹ̀. Ní èrò Oyè (2016), polisẹ́mì àti fẹ̀dàdọ́gba ń yorí sí pọ́n-na nítorí ẹ̀dá kan máa ní ìtúmọ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Kókó pàtàkì kan nípa àwọn ọ̀rọ̀-onítúmọ̀-púpọ̀ ní pé nínú àwọn ìtúmọ̀ tó ní, ọ̀kan jẹ́ olúborí, nígbà tí ìyókù jẹ́ àkànlò tàbí àfiwé lásán sí ìtúmọ̀ tí a ní lọ́kàn bí ó ṣe jẹyọ nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, níbi tí ìtúmọ̀ adámọ̀ **Orí** jẹ́ *Olórí*, ní (10a) ṣùgbọ́n ní (b àti d) **Orí** túmọ̀ sí Ẹlẹ́dàá tàbí Àyànmọ́. Polisẹ́mì dàbí àkọ́kọ́ nínú ẹ̀dà méje ti Empson (2003), mẹnubà nínú iṣẹ́ rẹ̀, níbi tí ọ̀rọ̀ kan ti ní ìtúmọ̀ tó pọ̀. Pẹ̀lú gbogbo àlàyé wọ̀nyí, a lè sọ pé polisẹ́mì (ọ̀rọ̀-onítúmọ̀-púpọ̀) jẹ́ ọ̀kan lára àtiwáyé fún pọ́n-na.

### 3.4. Àwọn ọ̀rọ̀ to kọ́wọ̀ọ́ rìn papọ̀

Àìdánilójú lórí àwọn ọ̀rọ̀ to kọ́wọ̀ọ́ rìn papọ̀ lè jẹ́ orísun tàbí ìṣẹ̀dá fún pọ́n-na. Nígbà tí ó bá ṣéeṣe fún ìhun méjì láti tọ́ka sí ohun kan náà nínú gbólóhùn, irú àyọkà bẹ́ẹ̀ jẹ́ onítúmọ̀ púpọ̀. Ullman (1970) pè é ní ẹ̀hun onítúmọ̀ púpọ̀ (àpólà gbólóhùn tàbí gbólóhun ti a lè túmọ̀ sí oríṣìíríṣì ọ̀nà/amifíbọ́lọ́jì). Àyọkà ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn àìdánilójú yìí:

11(i) Ọlọ́jọ́ dákun má jẹ́ ó pẹ́;
Ko tún wá jọba
**Àwọn baba ìyá mi ó fọwọ́ tì ọ́**
Ọ̀gẹ̀gẹ̀ bí baba ọmọ ti fọwọ́ tọmọ (Àlàgbé, 2006:19)

Ohun tó fa pọ́n-na nínú ọ̀rọ̀ tí a kọ yàtọ̀ lókè yí ni àìdánilójú tàbi àìleè sọ ní pàtó àwọn ọ̀rọ̀ tó kọ́wọ̀ọ́ rìn nínú àpólà gbólóhùn yìí tó mú pọ́n-na lọ́wọ́. Nítorí a ò mọ̀ bóyá ìrànlọ́wọ́ ìyá tó bí bàbá ẹni tí ó ń sọ̀rọ̀ ló ń béèrè fún, tàbí ti àwọn òbí méjèèjì, ìyẹn ìrànlọ́wọ́ bàbà àti ìrànlọ́wọ́ ìyá. Bákan náà nínú "Èèwọ̀ Òrìṣà", ti Ọlatubọsun fi gba àwọn èèyàn ní ìmọ̀ràn láti má ṣe fi ojú pa ẹnikẹ́ni rẹ́:

(ii) Idà kìí roròroró
Kó pàkọ̀ mì
<u>Ìkìlọ̀ àwọn àgbà</u>
Ajá kìí roròroró
Kó sì polówó (Ọlátúbọ̀sún,1977:28)

Ohun tí ó fa pọ́n-na nínú ọ̀rọ̀ ti a fàlà sí nídìí ni ìtúmọ̀ oríṣirí̀ṣi ti àwọn ọ̀rọ̀ tó ń kọ́wọ̀ọ́ rín papọ̀ yí ní. Bóyá;

(a) ìkìlọ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn àgbà fún ẹnìkan, tàbí
(b) ìkìlọ̀ láti ẹnu ẹnìkan sí àwọn àgbà

Lọ́rọ̀ kan, àìdánilójú lórí ohun ti akéwì ní lọ́kàn ló ṣokùnfà pọ́n-na. Bóyá àwọn àgbà ni kí ó bìkítà lórí bí wọn yóò ṣe máa bá ọmọdé àti àgbà lò, nítori ọgbọ́n ò pin sọ́dọ̀ àwọn àgbà nìkan tàbí ó jẹ́ ìkìlọ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn àgbà sí ẹnìkan, èyí tún ṣéeṣe. Àwọn ọ̀rọ̀ to kọ́wọ̀ọ́ rìn papọ̀ fara pẹ̀ ẹ̀dà kárùn-ún tí Empson (2003) mẹ́nubà nínú iṣẹ́ rẹ̀ níbi tí gbólóhùn tàbí làbárè kan ti ní ìtúmọ̀ púpọ̀.

### 3.5. Ìfàmìsí

Ìfàmìsí jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà ti pọ́n-na gbà ń wáyé. Ọ̀rọ̀, àpólà gbólóhùn tàbí gbólóhùn tí a ò bá fi àmì tí ó tọ̀ sí máa ń ṣòro fún òǹkàwé láti kà. Ẹ ṣàkíyèsí àwọn ọ̀rọ̀ tí kò ní àmì yìí nínú ewì "Ọba ọmọ́wọ́núọlá Oyèyọdé Oyèṣọsin Eléjìgbò Ti Èjìgbò", ti Àlàgbé kọ láti fi yin ọba àti bí àsìkò rẹ̀ ṣe tu ará ìlú lára:

12 (i) Ǹ jẹ́ ẹ̀ lè mú mi dé ẹ̀bùrù ọ̀nà àbùjá
Ilé Ìkirè ibi baba yín gbé n bẹrin?
<u>Àtàndá ọmọ ewú filé hàn mí</u> (Àlàgbé, 2006:17)

Nínú ọ̀rọ̀ ti a fàlà sí nídìí yìí, tí ó bá jẹ́ pé àmì ìdánudúró díẹ̀ wà níwájú **Àtànda** àti **ọmọ ewú**, ó túmọ̀ sí pé; **Àtàndá** ni olùwà tí ó ń tọ́ka sí ẹnìkan, **ọmọ ewú** jẹ́ ẹ̀yán sí Àtàndá tó jẹ́ olùwà, kí ó sin òun délé.

Àtàndá, ọmọ ewú, filé hàn mí = OL + EY
Àtàndá + ọmọ ewú filé hàn mí.

Bákan náà nínú àpẹẹrẹ yìí:

(ii) Olúlúfẹ̀ ọmọ Fásànyà (Ọlábímtán, 1969: 38)

Àìsí àmì ìdánudúró nínú gbólóhùn yí ló fa pọ́n-na. Tí àmì ìdánudúró díẹ̀ bá wà níwájú **ọmọ**, **olólùfẹ́ ọmọ** yóò jẹ́ olùwà tí ó ṣiṣẹ́ ẹ̀yán fún Fásànyà, tí yóò fún wa ní:

(a) [Olólùfẹ́ ọmọ] Fásànyà = ọmọ tí ó jẹ́ ààyò fún Fásànyà
Ṣùgbọ́n ti àmì ìdánudúró díẹ̀ bá wà níwájú Olólùfẹ́, **olólùfẹ́** jẹ́ ẹ̀yán fún **ọmọ Fásànyà**, yóò jẹ́:

(b) Olólùfẹ́ [ọmọ Fásànyà] = ọ̀rẹ́ minú tàbí àyànfẹ̀ ọkàn fún ọmọ Fásànyà
Lórí ìṣòro tí ó ń súyọ lórí ìfàmìsí, Fromkin àti Rodman (1993) sọ pé:
Tí a bá ṣafọ̀, ó ní iṣẹ́ tí a rán afọ̀ tí a ṣe. Nígbà tí a bá ń ṣafọ̀, ní àyé kan, ó yẹ kí a ṣètò àwọn ọ̀rọ̀ wa ní-pele ní-pele tí àlùbọ́sà ń to ọmọ tirẹ̀. Ṣùgbọ́n ní ọ̀pọ̀ ìgbà àṣìṣe máa ń wáyé nínú ìsọ̀rọ̀sí wa. A lè kálòlò, dánudúró díẹ̀ tàbi kí a ṣi ọ̀rọ̀ pè. Èyí sì lè yọrísí ọ̀rọ̀ onípọ́n-na.
Pẹ̀lú àwọn àlàyé wọ̀nyí, a lè sọ wípé, ọ̀rọ̀kọ́rọ̀ tí a ò bá fi àmì tó yẹ sí, lè yọrísí pọ́n-na.

**3.6. Ẹ̀dà-ọ̀rọ̀**

Púpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí ẹ̀dà-ọ̀rọ̀. Lára wọn ni Holman (1980), Ermidia (2005), Ọlatunji (2005), Fakẹ́yẹ (2014) àti Fáladé (2021). Holman (ninú Fálade 2012) ki ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí àkànlo-èdè ayàwòrán níbi ti ìtúmọ̀ ohun tí a ń sọ jẹ́ òdìkéjì ọ̀rọ̀ tó jáde lẹ́nu wa. Ó lè jẹ́ ọ̀rọ̀ àyẹ́sí ní ìrísí, ṣùgbọ́n a lò ó láti tàbùkù ohun kan ni, ó tún lè jẹ́ ọ̀rọ̀ tó ń tàbùkù ṣùgbọ́n tí a fi ṣe àyẹ́sí. Ní ojú ìwòye Ọlatunji (2005), ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ gẹ́gẹ́ bí àkànlo-èdè ayàwòrán ni a ti ń sọ òdìkéjì ohun tí a ní lọ́kàn jáde, tí ó lòdì sí ìtúmọ̀ ohun tí a fi wéra wọn. Ó jẹ́ ìtúmọ̀ tí kò bójúmu tí a wé mọ́ ọ̀rọ̀. Nínú èrò Ermidia (2005), ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ ní kí aṣafọ̀ máa pé ọ̀rọ̀ lẹ́kọrọ lái lọ tààrà. Fákẹ́yẹ (2014) ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ súyọ nípa lílo òdì ọ̀rọ̀ ti a ní lọ́kàn láti sọ. Nígbà tí Korg (1960) ń ṣàlàyé ìwúlò ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ nínú ewì, "ó sọ wí pé ọ̀nà míràn ti akéwi lè lò láti lo ìjásí láti rọ́pò ọ̀rọ̀ ṣákálá ni kí ó jẹ́ ki ọ̀rọ̀ tí yóò lò gbéwọ̀n, kí ó sì fi ìmọ̀lára tó lòdì sí ohun tí irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ dúró fún hàn. Nípa sísọ nkàn méjì tó takora nígbà kan náà, nípasẹ̀ ẹ̀dà-ọ̀rọ̀, ìtúmọ̀ kẹta yóò jáde nínú ewì". Pẹ̀lú àlàyé àwọn onímọ̀ wọ̀nyí, a lè pe ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ ní àìṣeédéé lááárín ohun tí a rò àtí èyí tí ó jáde. Nídìí èyí, a lè sọ pe ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára orísun pọ́n-na, bí ìtúmọ̀ òkè tí ọ̀rọ̀ ní ṣe ń yàtọ̀ sí ìtúmọ̀ ìpìlẹ̀. Bí ó ṣe hàn nínú àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí. Ìṣọ̀lá nínú 'Ikú Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọláṣùpọ̀ Ọ̀jẹ́dòkun', kẹ́dùn ikú ẹni rè tó dolóògbé, bí ó ṣe tiraka kàwé ṣùgbọ́n tí ikú pa lásìkòo tó yẹ kó máa jèrè gbogbo làálàá rẹ̀:

13 (i) Ọkọ Olú gbégbá orókè nígbà igba
Baba Fọláṣadé **<u>ò fẹsẹ̀kọ rí</u>**
Tó fi dọba l'ẹ́gbẹ́ afọgbọ́n-jẹun (Ìṣọ̀lá, 1978:11)

Kàkà kí akéwì sọ ní tààrà pé baba Fọláṣadé ò ṣe àṣìṣe lẹ́nu iṣẹ́ rí, ó lo ẹ̀gọ́ láti sọ pé kò fi ẹsẹ̀ kọ, tí èyí fi ààyè sílẹ̀ fún àwọn ònkàwé láti fún ọ̀rọ̀ yí ní ìtúmọ̀ tiwọn báyìí:
(a) kò gbá ẹsẹ̀ mọ́ nkàn rí
(b) kò wọ wàhálà ní gbogbo àsìkò tó lò lẹ́nu iṣẹ́.

Nínú "Nínú Ọgbà Ayọ̀", tí Ọlatúbọ̀sún kọ láti fi bí àwọn olólùfẹ́ méjì ti n fìfẹ́ hàn síra wọn;
(ii) Bá à kọ́ yààrá ńlá
Ìfẹ́ ṣe yàrá bò wá
Kóṣùpá ìfẹ́ ó máa ràn lọ́dọ̀ọ̀ wa
**<u>Ká dáná ìfẹ́</u>**
Ká wá kòkò ìfẹ́ síbi
Ká dira wa mú pé (Ọlátúbọ̀sún, 1977:9)

Nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, akéwì pé ọ̀rọ̀ sọ nígbà tó lo **ká dáná ìfẹ̀**, kàkà tí ì bá fi sọ pé "**ká ní àjọṣepọ̀**". Tí a bá tún wo "ikú Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọláṣùpọ̀ Ọ̀jẹ́dòkun" ti Ìṣọ̀lá;

(iii) Àní Ọláṣùpọ̀ Àrẹ̀mú ọmọ Ọ̀jẹ́dòkun
Tó ṣebí idán tó **yọ** nínú ẹgbẹ́ wa
Tó gbọ̀nà ẹ̀bùrú, ó yọ́ni sílẹ̀ láìtọ́jọ́ (Ìṣọ̀lá, 1978:11)

Akéwì kò fẹ́ sọ pé Ọláṣùpọ̀ Àrẹ̀mú ṣẹ́kú láàárín ẹgbẹ́ wọn, ó dà á pè nípa sísọ pé "ó ṣe bí idán tó **yọ** kúrò nínú ẹgbẹ́ wọn". Nínú "Àjọ̀dún Òmìnira Nàìjíríà", Ọlátúbọ̀sún fi ewì yìí kí àwọn ọmọ Nàìjíríà kú oríire, ó tún fi gbà wọ́n níyànjú láti yàgò fún ohun tí ó lè fa ìpínyà láàárín wọn:

(iv) A ti fira wa lògbòlògbò
A ti dara wa nídàkudà tán
A ṣe bẹ́ẹ̀ kúkú lọdún púpọ̀ lẹ́hìn òmìnira
Kídẹ̀ra ó wá wọ̀lú dé
Ká jọ máa gbádùn
Ǹjẹ́ ẹ má mà jẹ́ ó **dogbè**
Kẹ́ẹ má sì jẹ́ ó **dòfún** oòò
Bó bá ṣe bẹ́ẹ̀ tó bàjẹ́
Gbogbo aṣíwájú orílẹ̀ èdè yí
Yóò dorí ẹ̀yin nìkan (Ọlátúbọ̀sún, 1977: 64)

Nínú àyọlò òkè yìí, akéwì fẹ́ fi pẹ̀lẹ́ gba àwọn àgbààgbà nímọ̀ràn nípa bí nkan ṣe rí lórílẹ̀-èdè, èyí tí ì bá fi lo burú tàbí burújáì, ó pé ẹ sọ nípa lílo orúkọ àwọn odù méjì yìí; Ogbè àti Òfún tí ó túmọ̀ sí ohun tó búrú. Akéwì gbà pé òye ohun tí òun sọ yóò ti yé àwọn olùgbọ̀ tàbí òǹkàwé tí ó mọ àpadélúde èdè Yorùbá. Nínú "Ọ̀yìnyìn" Ìṣọ̀lá gba àwọn ọmọbìnrin nímọ̀ràn láti máa gbé ìgbésí ayé tó dára, kí wọ́n má bà á bímọ àlàìní baba lọ́jọ́ ọ̀la:

(v) Bọ́yìnyìn bá relé ẹyẹ
Wuruwuru a jẹgi
B'ó tún relé eku
Ẹlẹ́wírí a tún koná
Kò tọ́jọ́, kò tọ́ṣù
Kirindin gbanú ọ̀yìnyìn
Èèmọ̀ lukutu pẹ́bẹ́
Oyún la rí ọkọ dà? ( Ìṣọ̀lá, 1978:42)

Nínú àyọkà òkè yìí, akewì fi ẹ̀gọ́ sọ fún àwọn ọ̀dọ́bìnrin láti yàgò fún bíbẹ́ láti ọ̀dọ̀ ọkùnrin kan sí òmíràn, nítorí tí oyún bá dé, kí wọn má lọ bí ọmọ tí kò ní ni baba tàbí tí wọn ò ní lè mọ baba rẹ̀. Láti ínu àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, nínú ẹ̀dà-ọ̀rọ̀, a rí ìtúmọ̀ ìpìlẹ̀ tó yàtọ̀ sí ohun tí a sọ jáde lẹ́nu. Fún ìdí èyí, ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára ìṣẹ̀dá tàbí orísun pọ́n-na.

## 4. Àgbálọgbábọ̀

Iṣẹ́ yìí ti gbiyànjú láti wádìí àtiwáyé àti ìṣẹ̀dá pọ́n-na bí àwọn akéwì ti ń ṣàmúlò rẹ̀ nínú ewì Yorùbá. Lílo tíọ̀rì pọ́n-na ti Empson nínú ìlànà tíọ̀rì ìfojú- àátò-wo lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìlànà tí a fi ṣe àlàyé nínú pépà yìí, jẹ́ kí a mọ̀ pé pọ́n-na lè wáyé nípasẹ̀ àkànlò èdè, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, fẹ̀dàdọ́gba, Polisẹ́mí, àwọn ọ̀rọ̀ to kọ́wọ̀ọ́ rìn papọ̀, ìfàmìsí àti ẹ̀dà-ọ̀rọ̀. Nìwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé ìtúmọ̀ ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ àti àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ kìí lọ tààrà, tí ìtúmọ̀ wọn máa ń jẹ́ onípọ́n-na, àbùdá àdání ti ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ ní ni pé, a máa ń dà á pè. Nídìí èyí, ìtúmọ̀ tí ìhun òkè ní pọ̀ ju ti ìhun ìpìlẹ̀ lọ ti ó sì lè yọrí sí pọ́n-na. Ìtúmọ̀ oríṣiríṣìí tí a rí nínú

àwọn àpẹẹrẹ tí a lò nínú pépà yìí fi ẹwà tí pọ́n-na bù kún ewì hàn, bákan náà, ó fi pọ́n-na hàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀jẹ̀ àti ẹran jọ̀bọ̀jọ̀bọ̀ tó mú kí ewì dùn, kó tún rẹwà.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Abímbọ̀lá, W. (1972). *An expository of the Ifá literary corpus*. Ibadan: Oxford University Press, 1972.

Abímbọ̀lá, W. (2004). *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*. Apá kíní. Press of the Publishers, Collins and Co. Ltd, Glasgow, U.K.

Àjànàkú, A. (2004). *Orin Ewúro*. Atlantis Books, Ibadan.

Àkànmú, S. (2014). *New idioms and idiomatic expressions in Yorùbá literary discourse and routine communication*. Ph.D thesis. University of Ibadan.

Àlàgbé. A. (2006). *Ìjálá; Ògúndáre Fọ́yánmu*. Ògbọ́mọ̀ṣọ́: astra-J Creations.

_________. (2017). *A Lexico-Grammatical Interpretation of Ambiguity*. African Journal Online. Retrieved April 4, 2017. https:www.ajol.info>viewfile.

Awóbùlúyì, O. (1990). *Yorùbá metalanguage* vol. ii, Ìbadan: University Press Ltd.

Awẹ́, D. (2009). Ẹkún Elédùmarè. Ileṣa: Elyon Publishers.

Crystal, D. (1992). *An Encyclopedic dictionary of language and languages*. Oxford: Blackwell Publishers.

Currie, I. et.al. (1970). *The language of poetry*. London: Heinemann Educational Books Ltd.

Eleanor, C. (2009). *Ambiguity and the poets*, Retrieved September 2, 2016.http/www.connotations.debcook01813.htm>.

Empson, W. (2003). *Seven Types of Ambiguity*, in the idea of literature, the foundations of English Criticism. Moscow: Progress Publishers.

Ermidia, I. (2005). '*When Saying is not meaning' A Pragmatic approach to Humorous Ironies in Pragmatic* Today Cap Piotr Series: Lodz Studies in Language. Vol 12, 235. Barbara Lewandowska (ed).

Fálétí, A. *(1985). Ewì Adébáyọ̀ Fálétí, Ìwé Kíní*, Heineman Educational Books Ltd, Ibadan.

___________. *(1982). Ewì Adébáyọ̀ Fálétí, ìwé kejì*, Heineman Educational Books Ltd, Ìbàdàn.

Fákẹ́yẹ, F. (2014). *Irony and the Ironic in Some Selected Yorùbá Tragic Plays*. Ph.D thesis. University of Ibadan. Ibadan.

Fáladé, M. (2012). *The language style and pattern of the Yorùbá newspaper review in some selected radio stations*. M.A. Thesis. University of Ìbàdàn.

___________. (2021). *Linguistic Ambiguity in Yorùbá Poetic Discourse*. PhD Thesis. University of Ibadan.

Frath, P.(ed). (2000). *Polysemy, Homonymy, and References*. Proceedings of the JASGIL seminar, Strasbourg.

Fromkin, V., and Rodman, R. (1993). *An Introduction to Language*. fort Worth: Harcourt Brace Jovanovich College publishers.

_______. (1983). *An Introduction to Language*. Rinehart and Winston, New York.

Gurrey, P. (1968). *The appreciation of poetry*. London: Oxford University Press.

Holman, R. Honeck. (1980). '*Some Ambiguities in the study of Ambiguity*' in Gorfein DavidS(ed). Resolving Semantic Ambiguity. New York: Springer-Verlag New York Inc.

Ìṣọ̀lá, A. (1978). Àfàìmọ̀ ati àwọn àròfọ̀ míràn. Ibadan: University Press.

Adéyẹmí, L. (2001). *Iṣẹ́ Ọ̀rọ̀ Lámèyítọ́ Lítíréṣọ̀ Yorùbá*. Nínú Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá, Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà.

Shebiotiomo Publications.

Korg, J. (1960). *An Introduction to Poetry*. New York: Rinehart and Winston Press.

Kaufer, D.S. (1986). '*Understanding Ironic Communication*'. Journal of Pragmatics. Vol. 5, No. 6.

Leacock. (2000). *Polysemy: Theoretical and computational Approaches*. Oxford: Oxford University Press.

Mokgokong, P. (1975). *Context as the determinant of meaning with Special Reference to Northern Sotho*. Ph.D, Thesis. Pretoria, University of South Africa.

Ọlábọ̀dé, A. (1981). *The Semantic Basis of Metaphor and Related Tropes in Yorùbá*. Ph.D thesis. University of Ibadan.

Ọlábímtán, A. (1969). *Àádọ́ta àròfọ̀ pẹ̀lú àlàyé àti Ìbéèrè.* Ìbadan: Macmillan Education.

_________. (1974). *Ewì oríṣiríṣi*. London: Longman Nig Ltd.

Ọlátẹ́jú, A.O. (2005). *TheYorùbá animalmetaphor*.Nordic Journal of African Studies 14(3): 368-383. Retrieved September 10, 2016. http/www.scribd.com/doc/291693141/The –Yorùbá-Animal-metaphors-Analysis-and-Int.

Ọlátúnjí, O. (2005). *Features of Yorùbá Oral Poetry.* Ibadan: University Press Plc.

Ọlátúbọ̀sún, O. (1973). *Àròyé akéwì apa kíní*. Ibadan: Onibonoje Press and Books Ltd.

___________. (1975). *Àròyè akéwì apa kejì*. Ibadan: Onibonoje Press and Books Ltd.

___________. (2002). *Ẹ̀mì in mi ẹ̀mí rẹ*. Ibadan: Afọlábí Press Limited.

Olúránkiṣẹ́, O. (1987). *Ìjì ayé*. Ibadan: Onibonoje publishers.

Scheffler, I. (1979). *Beyond the Letter*. London: Routledge and Kegan Paul Ltd.

Sekgaila, J.C. (2000). *Linguistic ambiguity in Northern Sotho: saying the unmeant*. Ph.D Thesis, Rand Afrikaans University, Johannesburg.

Springer-Verlag Berlin. (2015). Verb sense discovery in Mandarin Chinese - A corpus-based knowledge–intensive Approach. Retrieved August 10, 2017. htpps:/www.Springer.com/978.

Oyè, T. (2016). *Transformational Grammar.* Lay of Ventures Publishing Educational Services. Ìbadan.

Ullman, S. (1970). '*Change of Meaning in Hungerford*', Harold, Robinson, Jay, and Sledd, James (ed). English Linguistics: An Introductory Reader. Illinois: Scott, Foresman and Company.

Yusuf, O. (2002). *Understanding English Usage*. Ìbàdàn: Joyful Printing Press.